# IṢẸ́-ISIN AWỌN ỌMỌ LEFI

**Numeri 3:5-17, 21-51; 4:1-33**

**ẸKỌ 90 – FUN AGBA**

**AKỌSORI: "Inu mi dùn lati ṣe ifẹ rẹ, Ọlọrun mi, nitõtọ, ofin rẹ mbẹ li aiya mi" (Orin Dafidi 40:8).**

**I Awọn Ọmọ Lefi: Ẹbọ Israẹli si Oluwa**

1. Nipa aṣẹ Ọlọrun ni a ya awọn ọmọ Lefi sọtọ fun iṣẹ-isin wọn, Numeri 3:5-10; 8:5-22; Deuteronomi 10:8, 9; 33:8-11
2. Aṣẹ yii fi anfaani ti awọn Ọmọ Israẹli ti sọnu hàn, pe ki gbogbo wọn le ni ipin ninu iṣẹ-isin Ọlọrun ki wọn si mu ifẹ inu Ọlọrun ṣẹ, pe ki a le ya orilẹ-ède naa si mimọ́ fun Un patapata, Numeri 3:11-13; Ẹksodu 13:1, 2, 11-13; 19:5, 6; I Peteru 2:5; Ifihan 1:6; 20:6
3. Ọlọrun paṣẹ fun Mose lati kà – tabi ya - gbogbo ọmọkunrin ati agba ati ewe ninu awọn ọmọ Lefi sọtọ, lati ọmọ oṣu kan soke, Numeri 3:14-17, 39; 4:46-49
4. Niwọn bi awọn akọbi ọkunrin Israẹli ti sọ anfaani lati ṣiṣẹ ninu ijọsin Oluwa nù, a fi awọn ọmọ Lefi dipo wọn, Lefi kan fun akọbi ọkunrin Israẹli kọọkan, ati ohun ọsin awọn ọmọ Lefi dipo gbogbo awọn akọbi ninu ohun-ọsin awọn Ọmọ Israẹli, Numeri 3:40-45; 18:15, 16; Ẹksodu 34:20
5. A gba ṣekeli marun-un marun-un fun irapada ẹni kọọkan ninu awọn ọrinlenigba-din-meje (273) akọbi Israẹli ti o kù, Numeri 3:46-51

**II Iṣẹ́ ti a Yàn fun awọn Ọmọ Lefi**

6. Gbogbo awọn ọmọ Lefi yoo wà labẹ abojuto Mose ati Aarọni Numeri 3:38
7. Idile Gerṣoni, ti i ṣe iran Gerṣoni, akọbi ọmọ ọkunrin Lefi ní ẹgbaa mẹrin din ẹẹdẹgbẹta (7,500) ọkunrin ati ẹni oṣu kan tabi ju bẹẹ lọ, ẹgbẹtala o le ọgbọn (2, 630) ninu wọn le ṣiṣẹ fun Oluwa, Numeri 3:21, 22; 4:38-41
   Wọn pagọ ni iha iwọ̀-oorun Agọ ajọ, Numeri 3:23, 24
   Itọju wọn si wà lọwọ Itamari ọmọ Aarọni abikẹyin, ti i ṣe alufaa, Numeri 4:28
   Awọn ni a fi itọju Agọ-ajọ, ibori rẹ̀ ati aṣọ isorọ ti ẹnu-ọna Agọ-ajọ, ati aṣọ-isorọ ati okùn ti agbala ati aṣọ-tita ti ẹnu ọna agbala lé lọwọ, Numeri 3:25, 26; 4:21-28
8. Idile Kohati, ti i ṣe iran Kohati, ọmọ ọkunrin Lefi keji ni ẹgbaa mẹrin o le ẹgbẹta (8,600) ọkunrin, lati ẹni oṣu kan tabi ju bẹẹ lọ, ẹgbẹrinla o din aadọta (2,750) ninu wọn le ṣiṣẹ fun Oluwa, Numeri 3:27, 28; 4:34-37
   Wọn pagọ lẹba Agọ-ajọ ni iha guusu, Numeri 3:29, 30
   Eleasari, ọmọ Aarọni agba, ti o wà laaye, ti i ṣe alufaa ni n ṣe olori wọn, Numeri 3:32; 4:16
   Wọn maa n ṣe itọju Apoti-ẹri, tabili akara ifihan, ọpa fitila, awọn pẹpẹ, aṣọ ikele ati gbogbo ohun-elo mimọ́, Numeri 3:31
   Wọn maa n tẹle eto ti a ṣe lati ọwọ́ Ọlọrun tikara Rẹ̀, Numeri 4:1-4
   Wọn gba itọni kinnikinni fun mimu ohun-elo kọọkan, Numeri 4:5-15, 32
   Mose ati Aarọni gba ikilọ leralera lati pa wọ́n mọ́ kuro lọwọ ikú ojiji ti o le ti ipa aṣiṣe awọn alufaa wa, Numeri 4:17-20
9. Idile Merari ti i ṣe iran Merari, ọmọ ọkunrin Lefi abikẹyin ni ẹgbaata o le igba (6,200) ọmọkunrin lati ọmọ oṣu kan tabi ju bẹẹ lọ, ẹgbẹẹdogun o le igba (3,200) ninu wọn le ṣiṣẹ fun Oluwa, Numeri 3:33, 34; 4:42-45
   Wọn pagọ si iha ariwa Agọ-ajọ, Numeri 3:35
   Itamari abikẹyin Aarọni ni o n ṣe abojuto wọn, Numeri 4:33
   Awọn ni o n ṣe itọju apako Agọ, ọpa-idabu, òpó, iho-itẹbọ ati awọn okun Agọ ati agbala ati gbogbo ohun-elo Agọ ati ti iṣẹ-isin, Numeri 3:36, 37; 4:29-33

## ALAYE

**Agbo Kekere**

Nigba ti Mose wà lori Oke Sinai ti o n gba Ofin lati ọwọ Ọlọrun, Aarọni ati Huri wà pẹlu awọn Ọmọ Israẹli ti a ro pe wọn ju aadọjọ ọkẹ lọ lọkunrin lobinrin ati awọn ọmọde. Ninu ẹkọ kan ti a ti ṣe kọja a ri i pe lara awọn alakoso ati awọn eniyan naa kò mu inu Ọlọrun dun rara, wọn si ti ṣe ere ọmọ maluu lati maa sìn dipo Ọlọrun Abrahamu. Ẹṣẹ wọn tubọ buru si i nigba ti wọn wi pe awọn ọlọrun wura yii ni o mú wọn jade kuro ni ilẹ Egipti.

Ọlọrun sọ fun Mose ohun ti o ṣẹlẹ ni ibudo, O si rán an lọ lati ṣe bi o ti tọ́. A ri bi Mose ti bọ́ si aarin Ọlọrun ati ọlọtẹ orilẹ-ede naa, ti o n jijakadi nigba gbogbo lati ri i pe wọ́n gbé orukọ Ọlọrun ga ninu ohun gbogbo, -- ati ju ohun gbogbo lọ, -- ati bi oun ti ṣe aṣeyọri bibẹbẹ fun wọn.

Ni akoko ti a fi ẹ̀ṣẹ awọn Ọmọ Israẹli hàn wọn, Mose pe wọn nija pe, "Tani wà ni iha ti OLUWA?" Ẹya ti o kere ju lọ laaarin orilẹ-ede naa, awọn ọmọ Lefi, ni o dahun nipa yiya ara wọn kuro lọdọ awọn eniyan ti o kù. Eyi ni lati mu ọkàn Mose eniyan Ọlọrun rẹwẹsi nigba ti o ri iwọnba awọn eniyan diẹ ṣinun ti o yàn lati ya ara wọn sọtọ fun Ọlọrun, ṣugbọn ó ṣe e ṣe ki Mose ti ni imurasilẹ tabi igbaradi lati ọwọ́ Ọlọrun ti o fi ifẹ rẹ fun, fun iru iṣẹlẹ bayii. Ki i ṣe eniyan ya-n-turu tabi ọgọọrọ ọmọ-ogun ni a maa n bá nidii iṣẹ Ọlọrun lati ipilẹṣẹ ayé wá. Jesu rán awọn ọmọ-ẹyin Rẹ̀ leti nigba ti O wà ni ayé pe "agbo kekere" kan ni yoo wà ti a ti pese àyè silẹ fun ni Ọrun.

**Anfaani ti o Sọnu**

A jẹ orilẹ-ede naa niya gidigidi ni ọjọ naa; nitori ki ilẹ to ṣú ẹgbẹẹdogun (3,000) eniyan ti o ri owurọ ọjọ naa ti di okú ni aṣaalẹ. Dajudaju ibanujẹ nla ni o gba ibudo kan lakoko naa, nitori awọn ti o padanu olufẹ wọn; ṣugbọn bi ọrọ alakoso wọn ti gun wọn lọkan tó, awọn Ọmọ Israẹli gbà pe adanu wọn yii pọ̀ ju ti atẹyinwa lọ. Wọn si n fẹ nisisiyii lati bá Ọlọrun ti wọn ti mú binu ti wọn si ti dẹṣẹ si laja, ati nitori eyi Mose tọ Ọlọrun lọ lati bẹ̀bẹ̀ fun wọn. Lẹyin ọjọ diẹ wọn ri ojurere ati aanu Ọlọrun gbà, atipo wọn ni Oke Sinai si fẹrẹ wá si opin.

O yẹ lati jẹ ki o di mimọ̀ fun wọn siwaju si i nnkan miiran ninu Ofin titun ti wọn ṣẹṣẹ gbà, ki wọn ba le mọ ohun ti iṣọtẹ wọn mú ki wọn sọnu. Awọn ọmọ Lefi paapaa kò i ti i mọ bi èrè ti igboya wọn yoo mú wa ba wọn. Ṣugbọn a kò fi wọn sinu adeedee pẹ lọ titi nitori kò pẹ ti Oluwa fi bá Mose sọrọ, O si wi fun un pe ki o mu ẹya Lefi sunmọ itosi, ki o si fi wọn fun Aarọni alufaa. Akọsilẹ iyasọtọ awọn ọmọ Lefi fun iṣẹ Oluwa (Numeri 8:5-22) sọ fun ni pe mímú wọn wá si itosi jẹ́ fifi wọn fun Oluwa, gẹgẹ bi ẹbọ lati ọwọ́ gbogbo orilẹ-ède Israẹli. A fi awọn ọmọ Lefi fun Oluwa gẹgẹ bi "ẹbọ ãye" (Romu 12:1).

Eto Ọlọrun ni akọkọ ni pe gbogbo awọn Ọmọ Israẹli ni lati jẹ oṣiṣẹ fun Oun Ọlọrun ninu eyi ti idile kọọkan gbọdọ ni ipa ti rẹ̀. Ki i ṣe pe ki ẹni kan jẹ́ aṣoju fun ẹlomiran ninu iṣẹ Ọlọrun, bikoṣe pe ki gbogbo orilẹ-ede naa jẹ ijọba alufaa (Ẹksodu 19:5, 6). Ni akoko awọn baba nla, olori idile kọọkan ni o n ṣe iṣẹ isin naa, tabi aṣoju wọn. Ṣugbọn nigba ti Ọlọrun mu awọn Ọmọ Israẹli jade kuro ni ilẹ Egipti ti O si dá akọbi wọn sí, O paṣẹ pe ki awọn akọbi naa jẹ́ iyasọtọ lati ṣe iṣẹ-isin Rẹ̀ (Ẹksodu 13:1, 2; 22:29).

Wo o bi eto naa ti logo to! Bawo ni i ba ti dara to – paapaa lonii – bi olukuluku idile ba bẹru Ọlọrun ti wọn si fẹ ya akọbi wọn sọtọ fun Ọlọrun! Wo o bi Ihinrere i ba ti yara tàn ká gbogbo ayé tó – ti i ba si tàn kalẹ ni akoko tiwa yii – bi idile Onigbagbọ́ kọọkan ba ya ẹni kan sọtọ fun iṣẹ Ọlọrun! Bawo ni ere awọn Onigbagbọ́ i ba ti pọ̀ to nigba ti Onidajọ gbogbo ayé ba kó wa jọ pọ̀ si iwaju Rẹ̀! Bawo ni igbesi-ayé ẹni kọọkan i ba ti kún fun ire, ayọ̀ ati alaafia to ni ayé yii, bi wọn ba mọ̀ pe wọn ni ipin ti o yanju ninu iṣẹ Ọlọrun! Ṣugbọn o ṣe ni laanu pe "awọn ọmọ Lefi" nikan, "agbo kekere" oloootọ naa!

A ti maa n gbọ́ pe kò si ẹni ti a fi agbara mú lati jẹ́ ọmọ-ogun Ọlọrun. Otitọ yii farahàn gbangba nihin nigba ti a yan awọn ọmọ Lefi dipo awọn akọbi Israẹli. Awọn ọmọ Lefi yọnda ara wọn nipa mimu iduro wọn fun Ọlọrun niwaju ogunlọgọ awọn Ọmọ Israẹli. Nitori wọn fẹ ṣe bẹẹ, Ọlọrun paapaa fun wọn ni aṣayan ipò ninu iṣẹ-isin Rẹ̀ (Matteu 10:32). Awọn ti i ba wà ni ipò yii gẹgẹ bi eto lati ibẹrẹ wa di ẹni àpatì nitori wọn kọ̀ lati yọnda ara wọn nigba ti ipe jade lati wá si "iha ti OLUWA." Ọpọlọpọ eniyan ni o wà lode oni, ti wọn mọ pe a ti pe wọn si iṣẹ kan pato fun Ọlọrun, ṣugbọn ti wọn kò ṣe iṣẹ naa nitori awọn pẹlu kò jade wá si iha ti Oluwa. Ṣugbọn ki o dá wọn loju gbangba pe ẹni kan lara awọn ti "agbo kekere" nibi kan ti yoo gba èrè dipo wọn, nitori wọn jẹ ipe naa wọn si n ṣe iṣẹ pẹlu otitọ ọkàn fun Oluwa wọn.

**Akoso Ọlọrun Leto Leto**

Kò si ibomiran ninu Bibeli ti a tun le ri eto ati ilana kinnikinni fun ifọwọsowọ pọ̀ ṣiṣẹ laaarin Ọlọrun ati awọn eniyan Rẹ̀, ati gbogbo ayé lapapọ, gẹgẹ bi iru eyi ti a gbé kalẹ leto leto ninu Ofin awọn ọmọ Lefi. Kò si ohun kan ti a fi silẹ lai bojuto bi o ti wu ki o kere tabi ṣe ainilaari to, ko si ohun ti a fi silẹ lai ṣe tabi ti a kan ṣe ṣá. Ohun gbogbo ni a darukọ ti a si fi si ipò lẹsẹẹsẹ gẹgẹ bi eto, bi o ti wu ki o kere, tabi ti o ṣe ainiyi tó.

Ọlọrun ki i ṣe olupilẹṣẹ ohun rúdurùdu, bẹẹ ni inu Rẹ̀ kò dùn si aiṣọkan laaarin awọn eniyan Rẹ̀ ninu iṣẹ isin Rẹ̀, ohunkohun iyowu ti o le fà á. Ni ti iṣẹ Ẹmi Mimọ́, i baa ṣe ninu ọkàn Onigbagbọ tabi ninu iṣẹ isin Ọlọrun, nibi ti irẹpọ ati ifimọ ṣọkan ba wà ni O ti maa n dabira. Kò ni ọna miiran ti O n gbà ṣiṣẹ bikoṣe pẹlu iṣọkan. Eyikeyi ti a ṣe ninu iyapa, tabi pẹlu ija, rudurudu, aibikita, tabi ainaani, dajudaju ki i ṣe labẹ itọni Ẹmi Mimọ, bikoṣe nipa imisi ẹmi èké.

Idile Kohati ni a yàn lati maa ṣe iṣẹ ti o ṣe ẹlẹgẹ ju lọ, eyi ni itọju awọn ohun ọ̀ṣọ́ inu agọ, Apoti Majẹmu, tabili akara ifihan, ọpa fitila, pẹpẹ ati awọn ohun-elo mimọ́. Gbogbo iwọnyi ni olori alufaa ati awọn alufaa oluranlọwọ rẹ̀ yoo ti kọkọ bò mọ́ránmọ́rán ki awọn ti yoo gbé wọn to wọ inu agọ, nipa eto yii ki yoo si ikú fun ẹnikẹni niwọn bi wọn kò ti fi oju ri awọn ohun mimọ́ ti Ọlọrun kilọ pe ki wọn má ṣe rí.

Awọn ọmọ Gerṣoni jẹ́ iran akọbi Lefi, ṣugbọn a kò fun wọn ni ipò ti o ga ju lọ ninu iṣẹ-isin Ọlọklrun. Eto Ọlọrun ki i ṣe deedee pẹlu aṣa ọmọ eniyan, nigba pupọ; Oun a pa eto ati ilana eniyan ti si apa kan lati mu ifẹ ti Rẹ̀ ṣẹ nigba miiran. Mose ati Aarọni wá lati idile Kohati, o si le jẹ pe a fi ipò ọlá yii fun iran Kohati laaarin awọn ọmọ Lefi nitori ṣiṣe oloootọ awọn eniyan Ọlọrun meji yii paapaa ni ti ododo wọn lakoko ti Ọlọrun fi arun bá orilẹ-ède Egipti jà.

Ọlọrun fi iṣẹ ti Agọ paapaa ati gbogbo isorọ ati aṣọ tita titi de agbala le awọn ọmọ Gerṣoni lọwọ. Ohun ti o pọ̀ ni o wà nihin lati maa gbé lati ibi kan de ekeji ati lati ibudo kan ni itẹsiwaju lọ si omiran; kẹkẹ meji ti wọn bò ni wọn fi n kó ẹru ohun mimọ́ wọnyii; maluu mẹrin ni o si n fa kẹkẹ naa. Awọn kẹkẹ ati maluu wọnyii jẹ́ ọrẹ atinuwa fun Oluwa lati ọwọ awọn ijoye Israẹli, ti i ṣe aṣoju awọn akọbi ti awọn ọmọ Lefi gba ipò wọn. Ifẹ ati iyẹsi rere yii ni o kun ọkàn awọn akọbi, bi o tilẹ jẹ pe a ti paarọ wọn, si awọn ti o ya ara wọn sọtọ fun iṣẹ isin Ọlọrun ati awọn ti yoo fi inu-didun yọnda ini wọn, ẹtọ wọn, ati anfaani wọn lati mu aṣẹ Ọlọrun ṣẹ! (Wo I Timoteu 5:17).

Idile ti o kù silẹ ni Merari, awọn ọmọ Merari ni o ni iṣẹ́ ti o wuwo ju lọ ninu idile mẹtẹẹta. Nitori eyi, Mose fun wọn ni kẹkẹ mẹrin ati ajaga maluu mẹjọ ninu eyi ti awọn ijoye Israẹli mú wá. Iṣẹ wọn ni lati ru awọn apako agọ,

ọpa idabu rẹ̀, opo rẹ̀, iho itẹbọ rẹ̀, eekàn ati okun wọn, pẹlu ohun-elo gbogbo ti o yẹ ni lilo lati gbé agọ naa kalẹ ni ibikibi ti Oluwa bá yàn ninu aginju. Nihin ni a tun ri bi eto Ọlọrun ti péye to, bi o tilẹ ṣe pe idile Merari ni o kere ju lọ -- nigba ti wọn ṣiro gbogbo ọmọkunrin bẹrẹ lati ọmọ oṣu kan lọ soke, sibẹ idile yii ni o ni ọmọkunrin ti wọn tó iṣẹ ṣe pupọ ni iye ju awọn idile ti o kù lọ, eyi si fun wọn ni oṣiṣẹ ti o pọ̀ julọ.

**Nigba ti Ọwọ̀n Awọsanma Ba Ṣí**

Ọna ti awọn ọmọ Lefi gba fi n ṣe iṣẹ wọn fi hàn pe leto leto ni iṣẹ Ọlọrun n lọ. Idile kọọkan ni iṣẹ ti rẹ̀ ti o n ṣe. A sọ fun ni pe "nipa orukọ" ni wọn fi n ka iye ẹrù wọn. Olukuluku wọn ni a fun ni ipò kan laaarin ẹgbẹ́ ti o jumọ n wọ́ lọ gẹgẹ bi ẹgbẹ ọmọ-ogun nla ti o dá ṣáṣá, nibi ti o jẹ pe bi ijafara kan ba lọ wà, ọpọlọpọ le ṣegbe. Eyi jẹ aworan iwà pipe Ọlọrun ati bi O ti fẹ ki a ṣe iṣẹ Rẹ̀ (Numeri 4:49).

Boya ni kutukutu owurọ nigba ti awọn Ọmọ Israẹli bá kọkọ jade lati inu agọ wọn ni wọn yoo ṣe akiyesi pe Ọwọ̀n Awọsanma ṣí kuro lori Agọ Ajọ ti o si n tẹ siwaju lọ sọna Kenaani. Boya nigba miiran ni akoko ẹbọ owurọ nigba ti wọn kọju si Agọ Ajọ ninu eyi ti wọn n ṣe apẹẹrẹ Ẹbọ Pipe ti ikú Olurapada. Ni igbakuugba ti o wù ki o ṣe lowurọ tabi ni aṣaalẹ, lọsan tabi loru, idaru-dapọ kò si. A kò ṣẹṣẹ fi waduwadu yan awọn ti yoo gbé Agọ ati awọn iṣura mimọ́ inu rẹ̀. Kò si ariwo tabi ariyanjiyan laaarin olukuluku awọn oṣiṣẹ nipa ojuṣe wọn. Ohun gbogbo n lọ deedee gẹgẹ bi Ọlọrun ti fi wọn si eto, lai si idarudapọ.

Olukuluku idile ṣe itọju agọ ti rẹ̀ ati ohun ini wọn miiran ṣugbọn idile Lefi ti a ti yàn yoo kọja lọ taara si Agọ-ajọ. Awọn ọmọ Lefi ẹlẹgbẹ wọn ti o kù ni n boju to nnkan ti wọn, awọn wọnyii naa si ni ere lọdọ Ọlọrun nitori wọn ṣe oloootọ pẹlu. Olukuluku ọmọ Lefi ni o ni ipin kan, olukuluku wọn ni o si le gba ere ni Ọrun.

Ni akoko ti awọn ọkunrin wọnyii ba de Agọ ajọ, Aarọni ati awọn ọmọ rẹ̀ yoo ti pari bibò awọn iṣura mimọ́ wọnni. Leto leto ni awọn ọmọ Kohati yoo wọle lọ ṣe iṣẹ ti wọn. Kẹkẹ ko si fun ẹru ti wọn. Ọlọrun ti paṣẹ pe awọn ti a yàn yoo maa ru Apoti majẹmu Rẹ̀, ọpa fitila, tabili, pẹpẹ, ati awọn ohun-elo mimọ́ ni ejika wọn.

Lẹyin naa ni awọn ọmọ Gerṣoni yoo wọle, wọn o si mu aṣọ tita ti agbala ati agọ isorọ ti agbala, wọn o ká gbogbo iwọnyi le ori kẹkẹ wọn. Lẹyin naa ni awọn ọmọ Merari yoo gbé ẹru ti wọn, wọn o si fi pẹlẹpẹlẹ tò wọ́n le ori kẹkẹ. Awọn ọmọ Gerṣoni ati awọn ọmọ Merari ni a fun laye lati wà ni iwaju awọn ọmọ Kohati ninu titò wọn lọ́wọ̀ọ̀wọ́ ni itẹsiwaju irin ajo wọn.

Nigba ti irin ọjọ kan ba pari, Ọwọ̀n Awọsanma a duro, awọn Ọmọ Israẹli si mọ̀ pe wọn ti de ibi ti Ọlọrun yàn lati pagọ sí. Idile kọọkan a si pa agọ ti rẹ̀ si iha Agọ Ajọ (ọ̀tún tabi osi, iwaju tabi ẹyin) gẹgẹ bi eto lati ibẹrẹ wá. Leto leto ni iṣẹ awọn ọmọ Lefi nihin yii pẹlu, gẹgẹ bi igba ti wọn tú Agọ naa palẹ ni ibẹrẹ irin-ajo. Awọn ọmọ Merari pẹlu gbogbo ẹru Agọ ati ti agbala, ẹru ti igi, idẹ, fadaka ati ti wura; nnkan wọnyii wuwo pupọ (awọn kan ṣiro iwọn rẹ̀ si ẹgbẹrun mọkanlelogun oṣuwọn irin – 21000 Ib), awọn ni yoo kọ́kọ́ dé, ti wọn o si bẹrẹ si fi opo kọọkan dolẹ si àyè rẹ̀. Awọn ọmọ Gerṣoni ni yoo tẹle wọn, wọn o wọle pẹlu awọn aṣọ tita ati isorọ gbogbo, awọn aṣọ onișẹ-ọna ti o lẹwa ni oriṣiriṣi awọ̀, ati awọn okùn, ati awọ fun ibori Agọ, gbogbo nnkan wọnyii ni wọn o fi si ayè ti ọkọọkan ni lati wà; nigba naa ni awọn Kohati yoo gbé awọn ohun-elo mimọ́ wọnni wọ inu Agọ lọ. Ko si idaduro, bẹẹ ni kò si idaru dapọ tabi rudurudu kankan.

Lẹsẹkẹsẹ ti Ọwọ̀n Awọsanma ba ti fi hàn fun awọn olori ati gbogbo Israẹli ibi ti wọn o duro, laaarin akoko kukuru Agọ Ajọ ti dide duro o si ti di lilò. Lai ṣe iyemeji ọpọlọpọ igba ni iṣẹ́ yii maa n pari si akoko ẹbọ aṣaalẹ. Lẹẹkan sii, ijọ eniyan Israẹli yoo ti duro olukuluku lẹnu ọna agọ ti rẹ̀ tabi ki wọn pejọ yika Agọ ajọ, wọn a maa gbadura ni ita bi irubọ ti n lọ lori pẹpẹ idẹ -- ẹbọ ti i ṣe apẹẹrẹ Ọdọ-Agutan Kalfari.

Iṣẹ isin Oluwa jẹ́ iṣẹ ti o logo ju lọ ti eniyan le ṣe, nigba ti a ba si gba ipè si iṣẹ naa a gbọdọ ka a si anfaani ti o tobi pupọ. Awọn anfaani ti eniyan ba sọnu maa n jẹ ohun abámọ̀ ati ibanujẹ ti igba ki i le wosàn, tabi parẹ́. "Ailábámọ̀ li ẹ̀bun ati ipe Ọlọrun" (Romu 11:29).

A tun rán wa leti ni ti otitọ yii pe ọna ti Ọlọrun wa ni o gbọdọ bori nitori kò si ọna ti eniyan kan ti o dara ti a le fi wé ọna Ọlọrun. Oun funra Rẹ̀ ni O n ṣe eto ipo olukuluku ninu iṣẹ isin Rẹ̀; Oun ni O n yan awọn iranṣẹ Rẹ̀; O yan iṣẹ ti olukuluku fun un. A si fi wọn si aye ninu Ijọ gẹgẹ bi o ti wu U. Ṣugbọn kò pari si ibẹ̀. Ọlọrun maa n pese fun aini awọn oṣiṣẹ Rẹ̀ ninu ayé yii, yoo si tun fun wọn ni èrè nikẹyin; ati ju bẹẹ lọ, Oun tikara Rẹ̀ jẹ́ ini wọn, ireti wọn, ayọ̀ wọn ati itunu wọn!

## AWỌN IBEERE

1. Darukọ ọna mẹta ti a pín ẹya Lefi sí.
2. Idile wo ni Mose ati Aarọni ti wá?
3. Ki ni ṣe ti a fi mú ẹya Lefi dipo awọn akọbi awọn Ọmọ Israẹli?
4. Ọna wo ni eyi fi yatọ si eto Ọlọrun fun Israẹli lati ibẹrẹ?
5. Fi iye awọn akọbi ọmọkunrin Israẹli ṣe akawe iye awọn ọmọkunrin Lefi lati ọmọ oṣu kan lọ soke.
6. Ta ni alabojuto gbogbo awọn ọmọ Lefi?
7. Ta ni alabojuto ẹgbẹ́ oṣiṣẹ kọọkan?
8. Ki ni ojuṣe ẹgbẹ́ oṣiṣẹ kọọkan?
9. Ẹkọ wo ni a le ri kọ́, ti yoo ran ni lọwọ ninu eto iṣẹ Ọlọrun lọjọ oni, nipa bi awọn ọmọ Lefi ṣe gbà n ṣiṣẹ ti wọn gẹgẹ bi aṣẹ ti a fun wọn?
10. Bi a ba gba Ẹmi Mimọ́ laye lati tọ́ wa gẹgẹ bi a ṣe gbọdọ gba A laye, ko ni si idaru dapọ tabi aiṣọkan ninu iṣẹ isin wa fun Ọlọrun. Sọ idi rẹ̀.